# ỌMỌ OGUN RERE

## 2 Timoteu 2:1-26

## ẸKỌ 415 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ṣāpọn lati fi ara rẹ hàn niwaju Ọlọrun li ẹniti o yéjé, aṣiṣẹ́ ti kò ni lati tiju, ti o npin ọ̀rọ otitọ bi o ti yẹ" (2 Timoteu 2:15).**

**I Awọn Ẹwa Ọmọ-Ogun Rere**

1 Ọmọ-ogun rere ti Jesu Kristi gbọdọ jẹ alagbara ninu oore-ọfẹ, 2 Timoteu 2:1

2 Ọmọ-ogun rere gbọdọ maa kọ́ awọn ẹlomiran pẹlu, 2 Timoteu 2:2

3 Ọmọ-ogun rere gbọdọ fi ara da ipọnju, 2 Timoteu 2:3

4 Ọmọ-ogun rere kò gbọdọ fi ohun kan di ara rẹ̀ lọwọ, 2 Timoteu 2:4

5 Ọmọ-ogun rere gbọdọ ja ni aiṣe eru, 2 Timoteu 2:5

**II Abayọrisi Jijẹ́ Ọmọ-Ogun**

1 Agbẹ ti o n ṣe laalaa ni o ni lati kọ́ mú ninu eso wọnni, 2 Timoteu 2:6, 7

2 Ọmọ-ogun agbelebu a maa fi ara da iya ni ọ̀pọlọpọ igba, 2 Timoteu 2:8, 9; Heberu 11:25

3 Ọmọ-ogun ni ileri ere nla, 2 Timoteu 2:10-13; Heberu 10:35

**III Awọn Ojuṣe Omọ-Ogun Rere**

1 O ni lati maa rán awọn eniyan leti ododo Ọlọrun, 2 Timoteu 2:14

2 Ọmọ-ogun rere gbọdọ ṣaapọn lati fi ara rẹ̀ hàn niwaju Ọlọrun gẹgẹ bi ẹni ti o yeje, 2 Timoteu 2:15

3 O gbọdọ ta gbogbo ẹkọ kẹkọọ nù patapata, 2 Timoteu 2:16-18, 23

**IV Ọla tabi Ailọla**

1 Ipilẹ Ọlọrun duro-ṣinṣin, 2 Timoteu 2:19

2 Awọn ohun-elo miiran ninu ile nla jẹ́ si ọlá, awọn miiran jẹ́ si ailọlá, 2 Timoteu 2:20, 21

3 Lati maa pe orukọ Oluwa lati inu ọkàn funfun jẹ́ ọ̀na si ọlá, 2 Timoteu 2:22

4 A fi dandan lé ori iwa pẹlẹ ati iwa tutu, 2 Timoteu 2:24-26

**ALAYE**

Episteli keji yii ti Paulu kọ si ọdọmọkunrin alabaṣiṣẹpọ rẹ̀ ninu Ihinrere Jesu Kristi, ni Episteli ti Apọsteli yii kọ gbẹhin ninu awọn ti o wà ni akọsilẹ ninu Bibeli. Ninu iwe yii, Apọsteli nla nì ti o mọ̀ daju pe akoko oun lati fi ayé silẹ sunmọ tosi, tun n rán Timoteu leti diẹ ninu awọn ojuṣe rẹ̀ gẹgẹ bi ọdọ-iranṣẹ Ọlọrun ninu Ihinrere ati gẹgẹ bi oṣiṣẹ lati jère awọn eniyan ti n ṣegbe fun Kristi.

### Jijẹ Onigbagbọ́ ti O Duro Ṣinṣin

Ori ẹ̀kọ́ yii n tọka si bi o ti jẹ́ danindanin to fun ọmọ-ogun Onigbagbọ́ lati gbé igbesi-ayé Onigbagbọ́ ti o duro ṣinṣin. Jijẹ Onigbagbọ́ ti o duro ṣinṣin jẹ́ ẹwà ti o ṣọwọn pupọ lati ri ninu ayé yii, ṣugbọn bi a ba wà ninu ẹgbẹ ogun Ọlọrun nitootọ bi a ṣe ni lati wà, yo ṣeeṣe fun wa lati maa gbé igbesi-ayé Onigbagbọ́ ti o duro ṣinṣin. A kò le bọ́ lọwọ idojukọ inunibini, fifi ọ̀rọ ba ni jẹ, ipọnju ati oriṣiriṣi awọn iṣoro miiran ti Jesi ti sọtẹlẹ pe yoo bá awọn ti n gbé igbesi-ayé iwa-bi-Ọlọrun ninu Kristi Jesu; ṣugbọn iwa ati iṣe wa yoo maa wú awọn oloootọ ati olododo eniyan lori, iye iru awọn ẹni bẹẹ ti a o bá pade ninu ayé.

Ipinnu Ọlọrun ni pe ki awọn ọmọ-ogun Jesu Kristi ni ihamọra ki wọn si wà ni ipo yiyẹ fun iṣẹ Oluwa wọn: "Nitorina, iwọ ọmọ mi, jẹ alagbara ninu ore-ọfẹ ti mbẹ ninu Kristi Jesu." Ihamọra Onigbagbọ́ ni Ọrọ Ọlọrun. Bi Ọrọ Ọlọrun bá n gbé inu ọkàn ati igbesi-ayé ẹnikẹni ti n ja ija rere ti igbagbọ́, iru ẹni bẹẹ ni aabo ti o daju.

Oluwa paṣẹ fun awọn ọmọ-ogun Rẹ̀ lati maa kọ́ awọn ẹlomiran pẹlu. Ninu ẹgbẹ́ ogun ti ayé, ọgagun kò ni àyè lati maa kọ́ ati lati maa paṣẹ fun awọn ti a ṣẹṣẹ gbà si iṣẹ́ ologun ni gbogbo ọgbọ́n

ati mẹbẹmẹyẹ iṣẹ́ ologun, ṣugbọn oun a fi iṣẹ yii lé ọwọ awọn ti o ti mọ ọwọ rẹ̀ ti wọn si ni iriri pupọ nipa iṣẹ́ ologun. Ojuṣe ti ọgagun ni lati ri pe awọn ọmọ-ogun rẹ̀ mọ awọn ofin iṣẹ ologun, ṣugbọn awọn agba ọmọ-ogun ti wọn ti ni iriri pupọ ninu iṣẹ ologun ni wọn n ṣe iṣẹ olukọni-lẹkọọ gan an. "Ohun wọnni ti iwọ ti gbọ́ lọdọ mi … ni ki iwọ fi le awọn olõtọ enia lọwọ, awọn ti yio le mã kọ́ awọn ẹlomiran pẹlu." Awọn ọmọ-ogun rere Agbelebu maa n kẹkọọ nipa Ihinrere wọn si maa n fi ẹ̀kọ́ naa ṣe iwa hù, ki i ṣe fun ire ti ara wọn nikan, ṣugbọn ki wọn ba le jẹ iranwọ fun awọn miiran pẹlu.

## Ifi Ara Dà

Idi pataki ti ikẹkọọ fi wà ninu ẹgbẹ́ ogun ni lati sọ awọn ọmọ-ogun di alagbara lati mu ki gbogbo wahala ti wọn yoo bá pade ni oju ogun le di ara fun wọn, ki ara wọn si mọ̀ ọ́. Timoteu ti kọ́ awọn koko ẹkọ́ Onigbagbọ́, ṣugbọn Paulu tun n fẹ́ ki ọdọmọkunrin ọmọ-ogun Agbelebu yii mọ̀ pe awọn ohun miiran ti o le ti o si ṣoro wà niwaju lati fi ara dà.

Bibeli ko ṣe apejuwe ọ̀na Ihinrere ni ọ̀na gbẹfẹ, ṣugbọn Ọlọrun ṣe ileri oore-ọfẹ ati agbara fun awọn ti o bá fara dà. "Ṣe alabapin pẹlu mi ninu ipọnju, bi ọmọ-ogun rere Jesu Kristi." Paulu kò tẹ́ ibusun oniyẹ fun Timoteu, bi ko ṣe ọna ti o kún fun ẹ̀gun, ti o ṣoro lati dojukọ, ninu eyi ti inunibini le dide nigbakigba. Ṣugbọn Bibeli kún fun ọpọlọpọ ileri fun ère nlánlà fun awọn ọmọ-ogun Agbelebu ti wọn ṣe oloootọ: "Iwọ bọ́ sinu ayọ̀ oluwa rẹ" (Matteu 25:23); "Nitori ère nyin pọ̀ li ọrun" (Matteu 5:11, 12); "Bi awa ba farada, awa ó si ba a jọba" (2 Timoteu 2:12); "A fi ade ododo lelẹ fun mi" (2 Timoteu 4:8); "Nwọn si wà lãye, nwọn si jọba pẹlu Kristi li ẹgbẹrun ọdún" (Ifihan 20:4).

## Awọn ti Wọn Fi Idánú Jọwọ Ara Wọn

Nigba ti eniyan ba fi idanu ara rẹ̀ fun iṣẹ́ ologun ti ayé, igbesi-ayé rẹ̀ bi eniyan kan ṣá ni aarin ilu dopin fun iwọn akoko ti o wà ninu ẹgbẹ́ ologun. Ni dandan yoo fi awọn ọrẹ rẹ̀ silẹ, iṣẹ́ rẹ̀, ati iru igbesi-ayé ti o ti n gbé ki oun ba le ṣe gbogbo ojuṣe ti i ṣe ti ọmọ-ogun. A sọ fun ni pe gbogbo iye awọn ọmọ-ogun Romu ti wọn pọ̀ pupọ ti ó wà ni akoko ti Paulu Apọsteli, ni a kò gbà laaye lati ṣiṣẹ agbẹ̀, iṣẹ òwò, tabi iṣẹkiṣẹ miiran ti yoo ṣe idiwọ fun wọn ninu ìpè wọn gẹgẹ bi ọmọ-ogun.

Bakan naa ni Ọrọ Ọlọrun n pe awọn ọmọ-ogun Onigbagbọ́ pe niwọn bi o ba ti le ṣeeṣe fun wọn ki wọn maṣe jẹ ki ohunkohun ninu nnkan ayé yii dí wọn lọwọ ki wọn ba le wulo pupọ ninu iṣẹ Ihinrere. Ni igba gbogbo ni Apọsteli Paulu maa n fi ọwọ rẹ̀ ṣiṣẹ lati pese fun aini ti ara, ṣugbọn ohun ti o leke ọkàn rẹ̀ ti o si jẹ ilepa rẹ̀ ni lati waasu Ihinrere Jesu Kristi fun gbogbo eniyan nibi gbogbo. Oun kò jẹ ki awọn nnkan ayé yii dí oun lọwọ tabi pa iṣẹ rẹ̀ ati ìpe rẹ̀ ninu Ihinrere lara. Ohun rere ni bi a ba fi igbesi-ayé ti Paulu ati apẹẹrẹ rẹ̀ ṣe awokọ tiwa.

## Èrè

Ọmọ-ogun ti o ba n ṣe iṣẹ rẹ̀ daradara, nigba miiran pẹlu ti o tun maa n ṣe tayọ iwọn iṣẹ ti rẹ̀, a maa n da a lọla nipa fifun un ni ẹbun nigba miiran. Nigba gbogbo ni awọn ọmọ-ogun maa n pọ́n awọn ẹbun bẹẹ lé. Ara awọn ọmọ-ogun miiran maa n yá kánkán si iṣẹ nitori nipa ṣiṣe bẹẹ wọn ni ọkàn lati gba ère. Ki ọmọ-ogun kan to le gba ère, o ni lati pa ara rẹ̀ mọ ninu awọn ofin ati eto iṣakoso ti ẹgbẹ ologun.

Awọn ọmọ-ogun maa n ni igbega bi wọn ba ti n mọ ẹ̀kọ́ ati ete iṣẹ ogun si; ṣugbọn sibẹ, wọn ni lati pa ofin ati eto iṣakoso iṣẹ ologun mọ́ patapata. Bẹẹ gẹgẹ, ọmọ-ogun Onigbagbọ́ gbọdọ maa jà laiṣe eru, ki o ma pa ara rẹ̀ mọ ninu gbogbo itọni Ọrọ Ọlọrun, bi o ba fẹ gba ère lati ọwọ Ọba awọn ọba. Ṣiṣe oloootọ ninu iṣẹ-iranṣẹ yoo fun wa ni ère, ninu ayé yii ati ninu ayé ti n bọ̀. Awọn Onigbagbọ ti o fi ẹsẹ mulẹ, ti o rin deedee ni a maa n yàn si ipo ọlá ati ipo aṣẹ laaarin awọn Onigbagbọ́. Sibẹ, bi o tilẹ ṣe pe a gbé oju fò wá dá ninu ayé yii, ti a kò si dé ipo ti ọkàn wa n fẹ́, ère yoo wà fun jijẹ oloootọ wa ninu iṣẹ ni ayé ti n bọ̀. "Ẹniti o ba si ṣẹgun, ati ẹniti o ba pa iṣẹ mi mọ́ titi de opin, emi o fun u li aṣẹ lori awọn orilẹ-ède: on o si mã fi ọpá irin ṣe akoso wọn" (Ifihan 2:26, 27).

## Rere ati Buburu

"Ṣãpọn lati fi ara rẹ hàn niwaju Ọlọrun li ẹniti o yéjé, aṣiṣẹ́ ti kò ni lati tiju, ti o npin ọ̀rọ otitọ bi o ti yẹ." Kikọ́ Ọ̀rọ Ọlọrun ni ẹ̀kọ́ ti o dara jù lọ ti o si tọna. Nigba ti Joṣua kó awọn Ọmọ Israẹli dé Ilẹ Ileri, a paṣẹ fun un ki o maa ṣe aṣaro ninu Iwe Ofin ni ọsan ati ni oru (Joṣua 1:8). Ọlọrun paṣẹ pe Ọba Israẹli kọọkan gbọdọ kọ Iwe Ofin Ọlọrun funrararẹ̀ ki o si maa ka a ni gbogbo ọjọ ayé rẹ̀

(Deuteronomi 17:18, 19). Paulu kọ iwe si Timoteu: "Titi emi o fi de, mã tọju iwe kikà, ati igbaniyanju ati ikọ́ni … Mã fiyesi nkan wọnyi; fi ara rẹ fun wọn patapata; ki ilọsiwaju rẹ ki o le hàn gbangba fun gbogbo enia" (1 Timoteu 4:13, 15).

"Ṣugbọn yà kuro ninu ọ̀rọ asan, nitoriti nwọn ó mã lọ siwaju ninu aiwa-bi-Ọlọrun." Ayé kún fun ọ̀pọlọpọ irú nnkan bẹẹ lonii, ni ọ̀pọlọpọ igba ni fifi ẹkọ giga ṣe bojuboju, ati imọ giga ati ohun ti a fi ẹtan pè ni ẹkọ ijinlẹ. Ọpọlọpọ ẹ̀kọ́ ti a fi ọgbọ́n ori gbé kalẹ ati imọran ti kò fi idi mulẹ ti wọn si lodi si Ọrọ Ọlọrun ni awọn eniyan fi n pa otitọ Ọrọ Ọlọrun kú ninu ọkàn ọpọlọpọ awọn akẹkọọ, ti wọn si n sọ igbagbọ́ wọn di yẹpẹrẹ tabi di okú ninu Ọlọrun. Ṣugbọn kò yẹ ki ọgbọn ayé yii kan le yí otitọ Ọrọ Ọlọrun po ninu ọkàn ẹnikẹni. Bi a ba gba Ọrọ Ọlọrun laaye ninu ọkàn pẹlu igbagbọ́ ti o lagbara, a o lè la ohunkohun ti a ni lati dojukọ ninu ayé yii kọja laibẹru ati laiyẹsẹ. Awa yoo mọ ohun ti o tọ́ ki a ṣe nigba ti a ba pade awọn itan asán ati ọ̀rọ ahesọ wọnyii: ki a ta wọn nù ni.

**Ipilẹ Ti O Daju**

Bi a ba wo o gẹgẹ bi ẹ̀da eniyan, iṣudẹdẹ iba bo Paulu Apọsteli, ọkàn rẹ̀ iba si poruru. O mọ pe ọjọ atilọ kuro ninu ayé fun oun ku fẹẹfẹẹ, o si ri i bi awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ̀ lati ibẹẹrẹ ti n kọ ọ silẹ, ti awọn ẹlomiran ninu wọn si n waasu ẹ̀kọ́ èké. Sibẹ ipo igbagbọ́ rẹ̀ ga pupọ: "Ṣugbọn ipilẹ Ọlọrun ti o daju duro ṣinṣin." Awọn eniyan le yipada, wọn si maa n yipada, ṣugbọn Ọrọ Ọlọrun ki i yipada lae. Bi a ba ti n ri aipe ati abuku oriṣiriṣi ẹsin to ati bi ifẹ-sẹmulẹ ẹ̀kọ́ èké ti n ba ni lẹru to, ni o yẹ ki a mu iduro wa ṣinṣin to lori otitọ kanṣoṣo yii: pe ohun ti Ọlọrun ti fi ipilẹ rẹ̀ lelẹ daju ko si ṣe e parun. Eyiini ni ipilẹ ti a kò le ṣí ni ipò. Eyiini ni okuta igun ile ti o lagbara, okuta Gibralta (odi nla) fun igbagbọ́ awọn eniyan Ọlọrun, awọn ti yoo duro gbọnin pẹlu otitọ Ọrọ Rẹ̀ Mimọ́.

"Oluwa mọ̀ awọn ti iṣe tirẹ̀." Ki i ṣe kiki pe Oluwa mọ awọn ti i ṣe ti Rẹ̀ nikan, ṣugbọn Oun ni o tilẹ ni wọn. Ohun iyanu ni pe ki Ọlọrun ni wa ni ini ti Rẹ̀. "O si pè awọn agutan tirẹ̀ li orukọ, o si ṣe amọ̀na wọn jade … Nwọn kò jẹ tọ̀ alejò lẹhin, ṣugbọn nwọn a ma sá lọdọ rẹ̀: nitoriti nwọn kò mọ̀ ohùn alejò" (Johannu 10:3, 5). Ọpọlọpọ ajeji ohùn wà ninu ayé lọjọ oni, ṣugbọn awọn agutan tootọ kò jẹ tẹle ajeji ohùn lẹyin ṣugbọn wọn yoo mọ ohùn Oluwa wọn, wọn yoo si tẹle E. Oun ti fi ẹsẹ wọn mulẹ si ọna ododo. O si ti fi nnkan kan pamọ sinu ọkàn ati ẹmi wọn ti o n fẹ tọ Ọ lẹyin, lati kọ eti-didi si ajeji ohùn ti o wà ninu ayé yii, ati lati tẹti silẹ titara titara lati gbọ́ ohùn jẹ́jẹ́ ti Oluwa wọn.

**Ninu Iwa Tutu**

Awọn itọni ti a fifun ni ninu 2 Timoteu 2:22-26 yanju kedere. Wọn ṣe alaye ki ni iṣẹ ọmọ Ọlorun kan si ẹnikeji rẹ̀. Ojuṣe olukuluku wa ni lati jẹ oluranlọwọ, agbani-niyanju, lati jẹ ẹni ti o kun fun ẹmi Alaanu Ara Samaria, lati ṣe gbogbo eyi ti o wà ni ipa wa lati gbé ẹnị ti o ṣubu nipa ti ẹmi dide.

Kò si ayọ ti o tayọ eyi ninu ọkàn ati igbesi-ayé ọmọ-eniyan ani lati maa yọ awọn ti o ti ṣubu si ẹba ọna. O ṣe ohun danindanin lati ṣe iranwọ. Lati jẹ́ iranwọ fun awọn ti aarẹ mú, lati gbé awọn ti o rẹ̀, ti o ṣubu, ti o si ṣe alailera dide, lati maa fi igboya kun ọkàn wọn pe ẹnikan wa ti o ni igbẹkẹle ninu wọn ati ifẹ tootọ lati ri i pe wọn dé ẹnu-ọna Ogo naa awọn ojuṣe wọnyii maa n fi ayọ̀ ati ọpọ ibukun si igbesi ayé ẹni ti o ba n ṣe wọ́n. Bi gbogbo wa ba ṣe nnkan wọnyii, a ó jẹ́ ọmọ-ogun rere ti Jesu Kristi.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni awọn nnkan ti a le pe ọmọ-ogun rere Jesu Kristi lati fara dà?

2 Ki ni ṣe ti ọmọ-ogun rere fi ni lati di ominira kuro ninu gbogbo idiwọ ayé yii?

3 Ewo ni ẹ̀kọ́ ti o tọ́ ti o si ṣe anfaani jù lọ?

4 Ki ni a ni lati ṣe pẹlu itan asán ati ọrọ ahesọ? Ki ni ṣe?

5 Ki ni ohun ti o duro ṣinṣin, laibikita fun ohun ti eniyan le ṣe tabi le sọ?

6 Bawo ni eniyan ṣe n dé ipò ọlá ninu eto ti Ọlọrun?

7 Sọ gbolohun ọrọ yii pari: "Mã sá fun ifẹkufẹ ewe …"

8 Ki ni nnkan ti o maa n mú ayọ̀ wá sinu ọkàn ati igbesi-ayé eniyan?